WANTED

Two An Advanced Apprentice Printers.

**Apply in person to:-**

Modupe Printing Press
16, Bamgbose Street
LAGOS.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE

Iwe Arofo ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE IMARO
APA KẸTA
LATI OWO
G. A. SOWUNMI
**Price 2/-**
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
**Postag Extra**

VOL. I No. 48, WEDNESDAY MAY 28, — JUNE 3 1958 KỌBỌ KAN

# 'AJIJA' Gbe Wundia Kan Lo, O Gbe Pada Ni ADELEBO

Kaduna A gbo irohin wipe ategun ajija gbe omo wundia kan lo fun odun mokandinlogun (19years), sugbon nigbati ajija na tun gbe pada de lehin odun ti a wiyi, o ti di Adelebo, o si ti bimo bi marun.

Nigbati a ṣe abere ẹhin wo wipe, kiloti rin irin na? Eyi ni itan ti obinrin na sọ fun ọba:- Ni ọjọ kan, nigba ewe mi ti nko ju ọmọ ọdun mẹsan lọ, mo lọ kiri agbọn nigboro ilu Hausa ni Jos bẹni mo pade ọkunrin Hausa kan ti o ṣeleri fun mi pe, on yio mu mi lọ sọdọ Baba mi nitori ẹniti mo wa lọdọ rẹ ko tọju mi to,, inu mi si dun lati ba lọ, nitori mo fẹran baba mi pupọ.

Mo tẹle ọkunrin na, o si mu mi lọ si abule kan ti nwọn npe n Wamba ni itosi ilu Jos, nibẹ ni on pẹlu ọkunrin na ngbe titi ti on fi dagba to ọkọ ni, ki ọkunrin na to wa fi on fun ọkunrin kan ni iyawo ẹniti orukọ rẹ njẹ Malam Garuba, ọmọ marun ni on si bi fun Garuba na.

Baba nla iya lo jẹ mi nigbati mo wa lọdọ Garuba, ko si sọna ti mo le gba fi ṣalọ titi o fi wa di larin ọsẹ yi ti mo ri a ye lati gbe ọmọ mi abigbẹhin sa jade kuro nibẹ. Ọmọ mẹrin ti o ku si wa lọdọ Garuba lọhun.

Gẹgẹbi ẹjọ ti ọmọbinrin na ro fun awọn Ọlọpa, awọn ọlọpa ṣi nwadi ọrọ na lọwọ. Awọn ọlọpa bere lọwọ ọmọbinrin na wipe, njẹ o mọ ọkunrin Hausa ti o ji ọ gbe? o dahun pe bẹni. Njẹ o ha le mu ọlọpa de ọdọ ọkunrin na bi? o dahun pe bẹni; ṣugbọn ọkunrin Hausa na ti ṣalaisi.

## IKILO FUN GBOGBO ENIA LORI SANDINI TI O LEWU NI JIJE

Olori onişegun, Dọkita Adeniyi Jones ṣe ifilọ wipe ki gbogbo gbo ṣọra nipa rira Sandini ti ko dara rara fun jijẹ ti a si nta kakiri Eko. Akiyesi ti ẹ ni lati ṣe nipa Sandini na ni wipe ko ni ( PEPA ) lara o si dabi enipe ẹgbẹ rẹ yọ Gugulu sita, nipa eyi, gbogbo ẹja inu rẹ ni o bajẹ ti ko si dara rara.

O si tun ṣe ikilọ wipe gbogbo ẹni ti o ba ni iru Sandini bayi, ki wọn gbinyanju lati ko wọn wa si ikan ninu ibiti ao darukọ wọnyi:—

1. Public Health Department — 42, Broad Street LAGOS
2. Glover Street Health Office — 4, Glover Street LAGOS
3. Ọbalende Health Office Ọbalende Raad, LAGOS•
4. Ebute - Metta Health Office— Glover Street/Simpson Street Ebute - Metta
5. Apapa Health Office — Near Apapa Dispensary APAPA

## AWON IWE KOSEMANI TI O WA NILE FUN TITA NISISIYI

| | |
|---|---|
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalın Ajẹbidan | 2/6d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan pẹlu Itumọ Ala | 20/- |
| Itan Aladun lede Yoruba | 3/- |
| Ajiran Ilu Oku | 3/- |
| Waka Bisiriyu Apalara | 1/- |
| Itumọ Ala ati Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Iwe Owe Yoruba | 3/- |
| Psalm Iṣẹgun Ajẹ ati Aiye pẹlu Turari | 17/6d |
| Turari Itaja, Ẹyọnu Ajẹ ati Adura | 10/6d |

Fi owo ọja rẹ ati 1/- ranṣẹ si :-

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

AWỌN IWE TI A ṢẸṢẸ FẸ TẸ JADE

Igbo Eşubeleke ( kikun ) 4/6d, Irin Ajo Ajanpako ( kikun ). 4/6d Ayunọrunbọ ati Panpalaṣọ 4/6d, Ajiran Ilu Oku ( kikun ) 4/6, Ṣebotimọ Ọrẹ mi 3/-, Mafarọ Ṣere 3/-, Igba ko lọ bi Orere 3/-

Akiyesi :- Ẹ o ma gbọ nigbati o ba jade

## IJAFARA LEWU

A FI eyi se ikede fun gbogbo enyin onkawe Irohin Imọlẹ pe lati ọsẹ to nbọ Ọgbẹni J. O. SHOYINKA yio bẹrẹ itan miran ti o wulo fun ẹnikẹni. Bakanna si ni Ọgbẹni FAGBEMI AJANAKU ẹniti a mọ ni (Agbọrọdun ninu ẹrọ asọrọ magbesi) yio bẹre tirẹ na.

Ọpọlọpọ lo ti wa fi orukọ silẹ fun gbigba, tabi ki o bere lọwọ awọn ti o nta Iwe Irohin KỌBỌ KAN PERE NI.

# IMỌLE

ẸSIN ORO WA:- IMỌLE DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*
**16, Bamgbose Street, Lagos**
Telephone:- **21985**

*London Office:-*
*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE
PUBLISHING DISTRIBUTING CO. LTD. MITRE HOUSE
177, Regent Street, London W. 1,

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN

EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)

Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mefa ati Kọbọ Mefa (6/6d)


# AIYE KOSI FUN ENIKAN RARA

ASIWERE enia lo ma nwipe irufẹ oun kosi, kosi ẹda ti ko mọ lode oni wipe orişirişi enia lo wa bi olowo ti wa bẹ na si ni Talaka ati paapa Alagidi ati ologundudu ti ko kọ o dara tabi ko dara.

OHUN pataki ti o mu wa kọ akọle wa ti ọsẹ yi ni nipa awọn Ọdọmọkunrin ati Ọdọmọbinrin wa asiko yi nitoripe pupọ ninu wọn, niwon ko nbere oju lọwọ oloju ki nwọn ma to gba a, şugbọn ọmọde kole ni akisa ko to ti Baba to-bi i lọmọ. Ti ọmọde ba mọ ọwọ wẹ yio bagbalagba jẹun pẹ.

ŞUGBỌN eyiti awa oniwe Irohin Imọlẹ nba nyin sọ yio jẹ iranlọwọ fun olukuluku ọdọ lokunrin ati lobinrin paapa fun igbesoke ati ilọswaju ilu wa Naijiria. Ọrọ Ọlọrun sọ bayi wipe, Ẹ lọ si ile aiye ki ẹ si ma kede si eti igbọ gbogbo awọn ti ko ni imọ ati oye, Ẹni iwaju ni yio kọ ero ẹhin lọgbọn

NITORINA a kesi ẹnyin ọdọ wipe ki ẹ kọgbọn lati ọwọ awọn agba iwaju lati ifarabalẹ jaiye lọwọ wọn ki ẹnyin ọdọ ba le ri jẹ ninu igbadun ominira to nbọ laipẹ, pupọ ni aye wa fun lati jẹ alakoso lehin ọla O DARA fun ẹnyin ọkunrin ati obinrin asiko yi paapa ẹnyin ti ẹ ti fi owurọ yin lepa ohun ti ẹ o jẹ ti ẹ o mu lẹhin ọla ti Ọlọrun nitu anu rẹ wa gbe yin si ipo giga nibi işẹ nyin o dọwọ nyin ẹ maşe gbagbe bi ipo yi ti nwun nyin bẹ ni o si nwun elomiran gbogbo Alangba lo sinu delẹ a ko mọ eyiti inu nrun'.

ENYIN ọdọ, etutu lo ma ni aiye, ma to agba, ma to ọmọde pẹlu, paapa awọn ti ko to iaja jẹ ko jẹran buşan, awọn be ni elenini Eşu beleke laiye. Nitorina ki e joko ara je. Owe kan sọpe "Guruşọ guruşọ agba to eru lotọ, şa le guruşọ ki o ma woran", ọrọ ko nmi mkun agbalagba, e maşe korikori wọle onile kiri, e maşe rin irin kode mada lese, e maşe woroworo lenu e ma si şe je onje ti yio fun nyin lọrun e mase wo awofin ki oju nyin ma fọ. Nitori eniti o şe jeje aiye foro emi re ambot ri eniti o wipe on ko ni şe jeje.


DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO-:

**MODUPE PRINTNG PRESS**

16, Bamgboşe Street, Phone 21985
LAGOS


# IDAHUN SI IBERE ADEWUNMI IBADAN

IMỌRAN fun Ọgbeni Adewunmi ti Ibadan ti o jade ninu iwe Irohin Imọlẹ Olọ-yinmẹmọ ti ọjọ ọgbọn oşu kẹrin ọdun yi

Imọran temi nipe awọn Baba wa lonpowe bayi wipe ọwọ oyin ni ọmọ araiye nba ni la wo ororo ati wipe Ẹsẹ giri nile anjọfẹ, ofẹ tan, ẹsẹ da.

Itumọ owe ti akọkọ nipe nigbati ọkunrin ko iti ni işọ lọwọ, obinrin na fi silẹ, o lọ fẹ ẹlomiran. Nigbati o wa ri wipe gbogbo nkan ndan fun o wa nbẹbẹ lati pada wa fẹ, ki ọgbeni na tun wa ranti wipe alejo ni owo ki Ọlọrun jeki o ma dara fun gbogbo wa bi ko ba dara mọ, obinrin a bẹsẹ rẹ sọrọ, ohun ti obinrin si njẹ lẹnu ni wọn mọ, wọn ko ranti ti ana anbọsibọsi ti ijẹta.

Nitorina gẹgẹbi ero temi ko yẹ ko tun fẹ obinrinn na mọ nitoripe oju ti yio ba ni kalẹ ki ti ati arọ şe ipin.

Modupẹ o Olotu iwaju lọpa ẹbiti nre si.

Emi ni,
A. Yussuf Enimakure

OLOTU, inu mi yio dun tiẹ ba le gbami laye lati dahun si ibere ọgbẹni Adewumi Ibadan. Idahun si ibere na kun fun ọgbọn ati oye, nkan ti mo ri nibẹ ti mo fẹ ki arakunrin mi na şe nipe kio mu ọkan kuro ni ara obinrin na, (owe) Awọn oni kokoma to sọ wipe "Ai si işẹ kosi owo", Nitori obinrin yẹn ko ba yin gba ero lati kọ isẹ yẹn yọri rara.

Gẹgẹbi lẹta tio kọ siyin ti mo kayẹn, Bibeli Sọwipe "Ẹhin oni rọju ni Ọlọrun Ọba wa" mo fẹ kiẹ ni irọju si kiẹ ni olufẹ miran, nitori yio jẹ ipalara fun yin tiẹ ba sọpe ẹo gba pada lọwọ ọkọ towa.

Lucky Photo Service,
Mushin.

Olotu, Idahun temi nipe bi obinrin na ko ba ti lọkọ miran kio gba pada.

Michael A. A. (Iludun)

Olotu, Gẹgẹbi ọgbọn temi bio ba pada wa, emi koni gba mọ, koba mi lawọ ẹjẹ, ko si yẹ koba mi lawọ epo.

A. M. Titiloye (Lagos)

## ọgbeni YEMI LIJADU Ni Ilu Oyinbo



OGBẸNI Yẹmi Lijadu ẹniti o ti nsọ ọrọ ninu ẹro gbohungbohun ni ilẹ Naijiria nkọ ẹkọ nipa ere şişe ti o ba işe rẹ lọ ni ilu ilu Oyinbo. Yio si duro fun oşu mẹta eyi jẹ Iranlọwọ ti 'BRITISH COUNCIL' şe fun. Nihin Ọgbẹni Lijadu ati Dọkita Tyrone Guthrie LI.D ẹni ti o gbajumọ fun eto ere şişe ni ile ẹrọ, ti o si ma nkọni ni ẹkọ nipa rẹ. O si gbajumọ papa nipa ere şişe ti a ti kọ si inu iwe paapa Iwe 'Shakespare'

Ni wọn igba ti Ogbẹni Lijadu ba si wa ni ilu Oyinbo yio ma lọ fun Ẹkọ nipa iru ere şişe bayi.

# PETE-PETE TANA NI POPA

OBERE LATI ỌSẸ TO KỌJA

Bi otilẹ jẹpe malu ni anjẹ, njẹ koti nitan? ẹwo ati igbati Jesu ti ku, nkan bi 1958 years, ẹ ko ti wa jẹ ẹran na tan, ẹ tilẹ wa sọ di ẹja Abu-bu-tan ni? mo mọ pe ẹlomiran yio dahun pe awọn fi nse Iranti ni, sugbọn iranti kinni ẹnse? Ẹko je lọ ranti ọjọ ti ẹnyin na yio fi aiye s'lẹ kẹ si ma tọrọ aforiji lọdọ Ọlọrun, nitori Jesu ti se iwọn ti o le se osi ti lọ ni Tirẹ.

(4) Isẹ kini ẹnyin Reverend ati Father sọọsi nse? abi gbogbo awọn ti ẹ ka nipa wọn ninu Bibeli ko sisẹ ni? sọ orukọ ẹnikan ninu wọn ti nwọn ko sisẹ fun mi. Jesu jẹ ọmọ gbẹnagbẹna, o si nse iṣẹ Kafinta, osi tun nse wasu fun awọn enia, Davidi jẹ Darandaran on na si tun nse wasu fun awọn enia.

Abi iwọ mo ju awọn ti mo darukọ wọnyi lọ? bi oba jẹpe iwọ Father rika pe Father tabi Reverend ko gbọdọ sisẹ mọ fẹ mọ, bi oba jẹpe bi iwọ koti sisẹ ni awọn ijọ rẹ ko sisẹ, ibo ni oti fe ri owo gba? abi o ma jale ni? sugbọn wọn ti mọ yin tẹlẹ ki wọn to fun yin ni orukọ "RẸBU-RẸDI".

Mase jẹki oju ti ọ nitoripe ojẹ Father tabi Reverend tete lọ wa isẹ rere se o, nitori awọn onigbagbọ miran nsọ pe awọn kole sisẹ fun Reverend, nitoripe orun pa on, ojo tun pa on ki on wa lọ ko lọ si sọọsi fun Reverend ti on gbadun ninu sọọsi, ti ara rẹ si tutu bi ara obinrin, wọn kuku joko nile wọn se ẹsin wọn ninu ile.

Mofi Reverend ati Farther silẹ, mo tun ta le awọn ọrẹ wa oni "Serafu" Alias:- "OMIYE" ẹ jọwọ ẹ mase rẹrin pupọ nitori wọn mumi ranti ọkunrin onilu ti o sọpe--Ẹ jẹ ka wi, ẹ je ka sọ, ẹ jẹ ka sọrọ sebi inu ile wa, ese yin ẹnyin Oniserafu? abi ese ti tiyin fi le bẹ? ẹ ma fi gbogbo igba so agbelebu mọ ọrun yin, se kale mọ pe Onigbagbọ ni yin, ẹle ṣe aṣe han ju, Ọlọrun ko si fẹ eleyi rara, se ẹnyin papa ka nipa awọn Farisi, pe ẹ ma se jẹki ọwọ ọtun mọ ohun ti osi nse, ẹrin pami kekekeke— —

Ẹnlọ si okun, kini ẹnlọ se gan? abi ẹfẹ bimọ ni, ẹro pe Ọlọrun ko mọ on ti onse ni? nitoripe o gba Mose la nipa okun, ẹnyin na wa nlọ si okun rẹirẹi, ṣugbọn nko ro pe nitori ọmọ ni ẹse nlọ nigbati ẹba de okun tan, ẹo wa ma se kokoro kan yio ma ja ni idi rẹ, iwọ ko si gbọdọ wo o, ati bẹ bẹ lọ, bẹ ni ẹ npe ara yin ni ẹni mimọ.

Ẹlọ sọra gidigidi ki ẹye se ohun ti Ọlọrun ko fẹ, emi nlọ ni yẹn, o tun di ọsẹ to nbọ ka to tun wo ohun ti takute yio mu, se ẹnyin mọpe ẹranko ni emi Pẹtẹ-pẹtẹ tana ni popa ndẹ takute na fun, asi ma mu gbogbo nkan ti o ba jade ninu iwe Irohin yi, njẹ ko yẹ ki nye dẹ takute na mọ? abi ki ntu bọ ma dẹ? gbogbo ẹniti oba fẹ ki nma dẹ nso ko kọ orukọ ara rẹ ransẹ si Olotu ko le tẹ erukọ wọn jade, bakanna awon ti ko ba fẹ, kẹ jọwọ kẹ mase gbagbe lati sẹ Iru ẹsin ti ẹnse pẹlu.

Olotu mo ngbadun rẹ ojare ma jẹki o su ẹ.

O DA BỌ O.

Oku diẹ Olotu, ma ti pari rẹ, jọwọ mai ti pari rẹ, ọro po pupọ nkosi rope ẹo le farada, nitori awọn akọwe lo nsọ pe "A sentence is a gbolohun which Ọmọluwabi cannot farada" se ẹnyin fẹ se iṣẹ Ọlọrun gan ni? Reverend ati Father ni mo ma nbi lere, ese ti ẹki le wasu ni gbangba ita fun gbogbo enia bi ti awọn ọrẹ mi Onimale? abi Jesu duro ni ilu Tirẹ ni onse wasu? emi rope on lọ si ilu kan de ekeji ni bi ẹnyin na bamọ pe ẹfẹ se ti Ọlọrun kẹ ma se iwasu nyin ni ita gbangba bi ẹko tilẹ le ma lọ ilu kan si ekeji, nigbati ẹ ba nse nita awọn enia yio ma bere ibere lọwọ yin ti ẹba si sọgun wọn mo mọ daju pe gbogbo wọn ni yio gba lati gba ẹsin yin gbọ.

Ṣugbọn nko rope enia le wọ inu Sọọsi wa lati bere ọrọ nipa Ọlọrun, bi oba jẹpe ẹ fẹ isẹ Ọlọrun nitotọ ẹni lati se ohun ti mo sọ yi, sugbọn lai ti se nko rope Irọ kọ ni ẹnpa.

# ISE TI IFE OW...

ISE ti ifẹ Owo gbon... ọmọ enia kodu ... ni wọndu, ifẹ owo ... masẹ :- ... yio de ti won ki yio ...

Ṣugbọn bi wọn ... Olukọ jọ fun ara w... yi eti wọn pada ku... Itan Asan nitori ifẹ o...

Baba ẹgbẹ Ijọ kofẹ ẹniti ofi Ijọ Ọlọrun le lọ. soju mọ, on wasu ti ... rẹ nikan ifẹ owo, gbong— ẹsẹ, olori ẹgbẹ kofẹ ri aw... ọmọ ẹgbẹ sọju mọ, nkan ... tun se iyanu ni wipe Baba ẹgbẹ ijọ Ake ti ọpọ Ijọ... osi tun ngbadura wipe, ki ijọ tiwọn fi on se Olori rẹ ma bajẹ, oju maribi, ẹsẹ malogunrẹ, ose bi owe, kosi ọrẹ otitọ mọ ayafi ọrẹ ọdalẹ, kosi oninu re kanmọ afi eyiti o ma wa ọna lati gba ibu gbe rere ẹnikeji rẹ ẹniti o kọwa ni ẹkọ ododo ibajẹ lafi nsan fun. Ehatise ti ẹnyin gbagbe Ọlọrun Ẹsan Psalm 94, ẹsẹ kini.

Kosi onigbagbọ otitọ mọ gege bi ti iṣaju, awọn toti-

LOHUN- IMARO ETA ... WUNMI Price 2/- TIMOTHEY Press ...ose Street, Extra ... 76 ... ation

# ...SE NMU OMO

Enia se lode oni, ..., ijọba aiye nikan Ọlọrun ko lese kobayi pe nitori Igba ye koro mọ.

... eti nrin wọn nkọ ... ara wọn, wọn o si ... wọn, wọn osi yipada si ... ẹsẹ.

... ọro Ọlọrun mu Ẹmi ... lelẹ, ati awọn enia rere ... toku nse ni ako jẹ k

Lati Ọwọ:—
...MỌ OLU—ARIBIYAN

...u wọn to ọrọ larin Ijọ Ọlọrun mọ, wọn ni wọn ko mọ semọ, ẹko ha ni sọra nipa ode di ode wa ki olukuluku sọra ninu ojusaju, eniti o ba ni owo nikan on ni onigbagbọ ode oni nbu ọla fun' nwọnko bọwọ fun ọjọ ori gegebi awọn Baba wa ti nse, eyi ko iyọnu ba orile ede wa, ati Ilu wa, ati agbo ile olukuluku wa.

(KOI TI PARI)

# Ogbeni V. O. OSULA Akeko Ise Irin.



Nihin a ri Ọgbẹni V. O. Osula (ẹni ọdun mejidinlọgbọn) ẹniti nkọ Ẹkọ nipa tito ati titu isẹ Irin ni ile isẹ Irin ni Ilu Oyinbo.

Ọdun Kẹta ti o si ti nkọ isẹ yi niyi, o si tun nkọ bi a ti se nlo awọn ẹrọ ti a nlo ni oko ti a ngbin nkan si.

